92

# IWE ITAN OGUN ATI ỌTẸ ILU-OKE

LATI ỌWỌ

Ọmọba J. B. Ogunjimi Losi

*Ẹniti o tẹ Iwe Itan Eko ati Itan Abẹokuta*

*Copyright*
*All Rights Reserved*

CHURCH MISSIONARY SOCIETY BOOKSHOP

LAGOS, WEST AFRICA

1933

90

# ỌRỌ ÌṢÍWAJU

O yẹ ki a ṣe ipamọ ìtan Ogun ati Ọ̀tẹ ti o ti ṣẹlẹ̀ lárin awọn ará Ibadan ati Ijẹṣa. Eyiti nwọn jà fun ọpọlọpọ ọdun ki o tó tán, ti a mọ̀, ti a npè li Ọ̀tẹ-ilu-oke. Laiṣiyemeji, o dara ki itan yi jẹ́ kikà ti iran-de-iran wa bi orilẹ-ède enia dudu ni ìha ìhin Afrika ; pe nigbati a bá ṣe ibẽre ìtan yi lọwọ awọn iran wa ti mbọ̀ lẹhin wa, ki nwọn le mọ̀ ọ sọ lati ipilẹṣẹ dé ipari. Pẹlupẹlu ẹ̀wẹ ohun iranti nla ni ọ̀tẹ nã mú wá, nitori ibi ati òfo ti ọ̀tẹ yi ti ṣe ko kere ni ilẹ wa. Nipa rẹ̀ ọpọlọpọ orile baba ati iya awọn enia wa li a tú ti a si sọ di ahoro. Ọpọ awọn õbí li a sọ d'opó, awọn ti o ti jẹ́ ọmọluwabi di ẹlẹru ni ilu-àjeji, ọ̀pọ ọmọ di alailõbi, ogunlọgọ di ẹni are ati alarinka nibi ọ̀tẹ dari wọn si ninu aiye.

Kini ohun tó jẹ anfãni fun awọn jagun-jagun ti ìgbana ? Afi òkiki, orukọ giga, iṣẹgun, iṣẹ-akọni, ìmẹ́ru l'ogun ati ikogun ọ̀pọ ohun alumọni lati ilu kan dé ekeji ló jẹ́ èro wọn. Ṣugbọn, igbe-iráhùn on ipohun-ẹkún ti awọn enia ní gbogbo ilẹ Yoruba ko ha pọ̀ ju gbogbo ère ti awọn jagun-jagun igbãnì ti jẹ ?

Nitorinã, èro ẹniti o kọ iwe Itan Ogun ati Ọ̀tẹ Ilu-oke yi ni pe, ki olukuluku enia tó bá ka a le mọ bi on yio ti ṣe mã mú alafia wá sãrin awọn ará Ilu rẹ̀, tobẹ̀ ti irẹpọ̀, ayọ̀ ati ifẹ-rere yio fi le mã wà ninu gbogbo enia ni ilẹ wa.

Itan yi jẹ́ eyiti mo ti tẹ̀ sinu iwe Irohin ti a npè ni "*The African Hope—Ireti Enia Dudu*," lati oṣù August 1919, titi dé December, 1921.

JOHN B. OGUNJIMI LOṢI,
*Ọmọba Abẹokuta.*

HEADMASTER,
St. John Evangelist's School,
Roman Catholic,
LAGOS, Nigeria.
1922.

# AWỌN OHUN TI O WÁ NINU IWE YI.


| ORI | | OJU-IWE |
|---|---|---|
| 1 | Ibẹrẹ Ọtẹ ati Ogun larin Ibadan ati Ijẹṣa | 1 |
| 2 | Ogun Ará ati Ipẹru ... ... ... | 3 |
| 3 | Ogun Ijẹṣa ati Iku Akere ... ... | 6 |
| 4 | Ogun Ogedengbe ... ... ... | 9 |
| 5 | Ogun Ekiti-Parapọ ... ... ... | 11 |
| 6 | Ogun Aiyede ... ... ... ... | 15 |
| 7 | Titu Ile-Ifẹ ... ... ... | 17 |
| 8 | Titu Ile-Ọfa ... ... ... ... | 19 |
| 9 | Ibẹrẹ Ilaja Nipa Alafin Ọyọ ... ... | 23 |
| 10 | Riran Awọn Onikọ si Kiriji Nipa Gomina Moloney | 25 |
| 11 | Ilaja Nipa Gomina Carter ... ... | 26 |